# ÌLÒ ÈDÈ NÍNÚ FÍÌMÙ *AGOGO ÈÈWỌ̀* TÍ AKÍNWÙMÍ ÌṢỌ̀LÁ KỌ

**TÁYÉ FATIMA SHEU**

**Department of Nigerian Languages,**

**Kwara State College of Arabic and Islamic Legal Studies,**

**Ìlọrin, Kwara State**

**Àṣamọ̀**

Nínú bébà yìí, a gbìyànjú láti wo bí Akínwùmí Ìṣọ̀lá ṣe lo èdè tó lóòrìn láti fi gbé fíìmù *Agogo Èèwọ̀* tó kọ jáde. Nínú iṣẹ́ yìí, a wo ohun tí fíìmù gangan fúnra rẹ̀ jẹ́. Fíìmù àti Àwùjọ Yorùbá, ìtàn inú fíìmù náà ní ṣókí. A tẹ̀síwájú láti wo bí òǹkọ̀tàn náà ṣe lo àwọn ọnà èdè nínú fíìmù rẹ̀ tí fíìmù náà ṣe jẹ́ ìtẹ̀wọ́gbà nínú àwùjọ wa.

**Kín ni Fíìmù?**

Ìwé atúmọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì kan tó ń jẹ́ Collins English Dictionary fún fíìmù ní ìtumọ̀ yìí. Ó ní:

> Film consist of moving pictures that have been recorded so that they can
> be shown at the cinema or on television.

Ìtumọ̀:

> Fíìmù jẹ́ ohun tó kún fún àwòrán wíwò, tí wọ́n gbà sílẹ̀ láti le jẹ́ kó di
> wíwò nílé fíìmù tabo lórí tẹlifíṣàn.

Tí a bá wo ìtumọ̀ tí atúmọ̀ yìí fún fíìmù, ó ṣe rẹ́gí torí pé ilé fíìmù tàbí inú ilé ni a ti ń wò wọ́n, bó tilẹ̀ jẹ́ pé, báyìí a ti ń wo fíìmù lórí ẹ̀rọ fíìmù alágbèéká wa, kò sí ibi tí a kò tilè wo, ní ìgbàkúùgbà tí ó bá wù wá.

**Ìfáàrà**

Onírúurú bí aṣọ alágẹmọ ni àwọn fíìmù tó ń jáde ní èdè Yorùbá ní ojoojúmọ́ báyìí. Àwọn fíìmù wọ̀nyí ni wọ́n gbé jáde láti fi ṣe ìṣípayá àti láti fi ta àwọn ènìyàn lólobó ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ tẹ́lẹ̀ tàbí àwọn ìhun àríwòye ohun tí ó ṣe é ṣe kí ó ṣẹlẹ̀ lọ́jọ́ iwájú tàbí èyí tí ó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́ lọ́wọ́. Tí ẹnu

kọ́ tètè bọ̀ọ̀lì sì kọ́ rárá bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa fíìmù ṣíṣe àwọn ẹ̀yà Yorùbá kò kẹ̀rẹ̀ rárá nípa kí á ṣe fíìmù láti fi gbé àṣà lárugẹ, dánilárayá àti láti fi kọ́ ni lẹ́kọ̀ọ́. Tí a bá sì fi ojú inú wò ó. Ó sòro fún wa láti rí fíìmù kan tí wọ́n gbé jáde tí kì í ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwùjọ.

Ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn fíìmù tí ó gbajú gbajà tí ó sì ń fọ̀nà àbáyọ han àwùjọ lórí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kọ̀ọ̀kan ni fíìmù *Agogo Èèwọ̀* jẹ́. Ó jẹ́ fíìmù Yorùbá tí ó jẹ mọ́ ìṣèlú, kókó inú rẹ̀ sì ń ṣe àfihàn àwùjọ olóṣèlú bákan náà ni ó ṣe àfihàn àṣà Yorùbá lọ́kan-ò-jọ̀kan. Nínú fíìmù *Agogo Èèwọ̀* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá gbé jáde yìí. A wo bí ó ṣe gbé fíìmù náà kalẹ̀ àti bí ó ṣe lo àwọn ọnà èdè nínú fíìmù náà.

## FÍÌMÙ ÀTI ÀWÙJỌ YORÙBÁ

Ní ọdún 1977 ni fíìmù ṣíṣe kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ láàárín àwọn ẹ̀yà Yorùbá. Eré fíìmù àkọ́kọ́ tó kọ́kọ́ jáde ni *"Àjàní Ògún"* tí ẹgbẹ́ òṣèré Adé Love (Adéyẹmí Afọláyan àti Dúró Ládiípọ̀) jọ ṣe. Ní kété tí fíìmù yìí dórí àtẹ ni àwọn àgbà òṣèré bí i olóògbé Hubert Ògúǹdé àti Moses Ọláìyá náà bẹ̀rẹ̀ sí ṣe akitiyan láti máa ṣe eré fíìmù. Ní ọdún 1978 ni òǹkọ̀wé Ọlá Balógun náà kọ fíìmù Yorùbá tí ó pe àkọlé rẹ̀ ní Money Power. Lẹ́yìn èyí ni àwọn ènìyàn jànkàn-jànkàn bí i Hubert Ògúǹdé bẹ̀rẹ̀ fíìmù ṣíṣe àwọn eré tí ó ti ṣe lórí ìtàgé tẹ́lẹ̀ ni wọ́n ṣe sínú fíìmù àwọn bí i: "Ayé" ní ọdún 1979, "Jáyésinmi", "Àròpin ń tènìyàn àti Ayànmọ́".

Bákan náà ni Adélékè (1995) àti Àlàmú (1990) jẹ́ kó di mímọ̀ pé láti 1977 ni fíìmù ti fi ìdí múlẹ̀ tó di gbajúgbajà láwùjọ Yorùbá. Adélékè àti Àlàmú jẹ́ ká mọ irú ipò tí fíìmù ṣíṣe wà ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ní ilẹ̀ Áfíríkà lápapọ̀. Ó ní kò sí orílẹ̀-èdè ní ilẹ̀ Áfíríkà tí ó ti ṣe àṣeyege nínú fíìmù ṣíṣe tó orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Iṣẹ́ takun takun tí ó ṣe é tọ́ka sí ni iṣẹ́ tí àwọn ẹgbẹ́ òṣèré Yorùbá ń ṣe láti mú kí fíìmù tẹ̀síwájú àti pé àwọn ẹgbẹ́ òṣèré Yorùbá ìgbà nì ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ẹgbẹ́ òṣèré tí ó fi ìdí múlẹ̀ jùlọ. Títí di òní yìí, àwọn ẹgbẹ́ òṣèré Yorùbá yìí náà ni wọ́n ń kó ipa pàtàkì jùlọ nínú fíìmù ṣíṣe síta lóde òní. Fíìmù ṣíṣe sì ti gboyè lọ́wọ́ eégún aláré àti eré orí ìtàgé tí a mọ̀ tẹ́lẹ̀. Ṣùgbọ́n ohun kan tí òǹkọ̀wé àti onífíìmù gbọdọ̀ gbájú mọ́ ni kí a fi bí àwùjọ wa ti rí hàn. Bí àwùjọ wa ṣe ń dàgbà, tó ń yí padà bẹ́ẹ̀ náà ni lítíréṣọ̀ wa lẹ́ka-ń-ka gbọdọ̀ mọ yí padà láti lè bá ìgbà mu.

## ÌTÀN FÍÌMÙ *AGOGO ÈÈWỌ̀* NÍ ṢÓKÍ

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ó kù ni ìbọn ń ró ní Ọ̀jọ̀gbọ́n Akínwùmí Ìṣọ̀lá fi ìtàn fíìmù yìí ṣe. Ọdún 2002 ni fíìmù náà jáde nítorí pé ìtẹ̀síwájú ni ó jẹ́ fún fíìmù Saworoidẹ. Agogo Èèwọ̀ jẹ́ apá kejì

fíìmù Saworoidẹ, gẹ́gẹ́ bí orúkọ eré yìí, ó fihàn wá wí pé àbọ̀ ń bọ̀ wá bá òsìkà tí ó ṣiṣẹ́ ibi, tí bini bini yóò bini tí bèèrè bèèrè yóò sì bèèrè. Akínwùmí Ìṣọ̀lá ṣe àgbékalẹ̀ fíìmù yìí ni èyí tí ó jẹ́ wí pé lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n ti rẹ́yìn àwọn ọba afipájoyè làtàrí lílo Saworoidẹ, àwọn ìjòyè kan náà wà tí ó tún kún fún ìwà ìbàjẹ́ lọ́wọ́ ní ìlú Jogbo, àwọn ni wọ́n ní kólè wá jà tí wọ́n á tún pé kí olóko wá mú un.

Ní kété tí ọba Adébọ̀sípò jẹ tán ni àwọn ìjòyè bẹ̀rẹ̀ ìwà jẹgúdújẹrá, ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé ọba ni òun fẹ́ ayipade àti ọ̀nà àti mú ayé dẹrùn fún àwọn mẹ̀kúnnù. Èyí ni ó ṣe okùnfà Orò *Agogo Èèwọ̀* tí wọ́n ṣe ní ìlú, èyí sì wà fún àwọn olóyè gẹ́gẹ́ bí Saworoidẹ ṣe wà fún Ọba ní ìlú Jogbo, bẹ́ẹ̀ náà ni Orò*Agogo Èèwọ̀* jẹ́ fún àwọn ìjòyè tí wọ́n sì ní kí wọ́n búra lọ́jọ́ ìbúra yìí, ibẹ̀ ni àṣírí ti tú tí àwọn ìlú sì ríi wí pé èniyàn ló ń bẹ nìdìí orò tí orò fi ń dún. Nínú àwọn olóyè tí ó ń ṣe ìbàjẹ́ wọ̀nyí, ni ọjọ́ ìbúra náà, àwọn kan jẹ́wọ́ lára wọn ni olóyè Badà àti ìyálóde nígbà tí olóyè Sérìkí àti olóyè Balógun kọ̀, èyí ni ó sì fa ikú wọn ní gbàgede ìbúra ní iwájú ilé Ọba. Látàrí inú rírun tí ó pa wọ́n.

**ÌLÒ ÈDÈ NÍNÚ FÍÌMÙ *AGOGO ÈÈWỌ̀***

Ọ̀kan pàtàkì lára èròjà tí ó máa ń fa adùn iṣẹ́ lítíréṣọ̀ yọ ní èdè jẹ́ èyí sì wà lọ́wọ́ bí òǹkọ̀wé bá ṣe mọ èdè lò sí. Gẹ́gẹ́ bí Oyèwọlé 2002, ṣe sọ nínú ìwé ìléwọ́ rẹ̀ pé:

> Èdè lọ́wọ́ òǹsọ̀tàn dà gẹ́gẹ́ bí irin lọ́wọ́ alágbẹ̀dẹ, tí ó lè fi dá àrà
> tí ó wù ú.

Ìyẹn ni wí pé adùn ìtàn wà lọ́wọ́ irú èdè tí a bá fi sọ̀tàn.

Akínwùmí Ìṣọ̀lá gẹ́gẹ́ bí ojúlówó ọmọ Yorùbá tó mọ ẹ̀wọ́n èdè tí ó sì mọ ìjìnlẹ̀ èdè Yorùbá dunjú. Ó ṣe àmúlò oríṣìíríṣìí ẹwà-èdè tí ó jinlẹ̀ tí ó sì fi àwọn akópa náà hàn gẹ́gẹ́ bí ọmọ ọ̀dọ̀ àgbà tí ó sì ní làákàyè, èyí jẹ́ kí eré náà dùn, tí ó fi di àwòtúnwò fún tọmọdé tàgbà. Akínwùmí Ìṣọ̀lá fi àwọn ìpèdè tí ó fi àwọn akópa nínú fíìmù yìí hàn gẹ́gẹ́ bí ọmọ Yorùbá tí ó gbọ́ ìjìnlẹ̀ èdè nínú ìṣọ̀rọ̀ àti ìgbóhùn jáde wọn. Ó hàn gbangba wí pé àwùjọ Yorùbá ni ó fi hàn nínú eré rẹ̀. Òǹkọ̀tàn náà lo àwọn ìlò èdè bí i ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀, òwe, àkànlò èdè, àwítúnwí èrò, àwítúnwí, àkùdé gbólóhùn, orin, ọfọ̀, àwíṣẹ, àmúlùmálà ẹ̀sìn, ìfọ̀rọ̀dárà.

Akínwùmí Ìṣọ̀lá lo àwọn ìpèdè ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ bí i:

> Olójú méjì asèsè odó

Oloju méjì á ṣe Kàdúná

Béèyàn ò lójú mẹ́fà kò le sèlú jogbo

Ẹlẹ́nu méjì á sèbàdán

Ẹlẹ́nu méjì á sèkó

Béèyàn ò lẹ́nu méjìlá kò le sèlú jogbo ...

Bàbá Ọ̀pálámbá ló sọ èyí nígbà tí eré náà bẹ̀rẹ̀ tí ó ń ronú lórí ọ̀rọ̀ ìlú jogbo.

Bákan náà èyí tí a tún gbọ́ lẹ́nu olóyè Séríkí nígbà tí ó di wí pé àṣírí ìkọ̀kọ̀ wọn fẹ́ máa tú, náà tún fi ìdí ìjìnlẹ̀ èdè yìí múlẹ̀. Ó ní:

Ẹ ò mọ̀ wí pé láfẹjọ́ sún a máa gbàrànmọ́

È é ṣe tí ó fi fẹ́ dun adájọ́ yín ju láfẹjọ́ sùn lọ

Ẹ jẹ́ kí lárojọ́ náà ó sọ tí ẹ̀ náà.

Oríṣìí àwọn ìpèdè báyìí tó jẹ́ Yorùbá pọ́n-ń-bélé ló wọ́pọ̀ nínú fíìmù yìí lẹ́nu àwọn akópa èyí tí ó fi hàn wí pé ojúlówó ọmọ Yorùbá ni àti pé àwùjọ Yorùbá ni Ìṣọ̀lá ń ṣe àfihàn rẹ̀.

**ÒWE**

Akínwùmí Ìṣọ̀lá fẹ́ràn òwe lílò nínú iṣẹ́ rẹ̀ púpọ̀, bí ó ṣe ń lo òwe àsínpọ̀ náà ló tún lo ẹyọ òwe tí ó fi wọ́n sẹ́nu àwọn akópa rẹ̀ láti fi àwùjọ Yorùbá hàn dunjúdunjú. Lára àwọn òwe tó sún yọ nínú fíìmù náà nìyí.

Mo dàgbà n ò ṣoge mọ́, owó ni ò sí.

Bí a bá ní kí wèrè ó sòkú ìyá ẹ̀, bí ó ṣe wù ú,

Ó lè sùn ún jẹ.

Baálé ilé kú ẹ tún fẹ́ m’ólókùnrùn joyè

A kánjú tu olú ọrán.

A tún rí òwe mìíràn gbọ́ lẹ́nu Ọba Bọ̀sípò nígbà tí òun àti olórí Ojúọlápé ń sọ̀rọ̀ lórí bí ìwà ìbàjẹ́ ṣe gbilẹ̀ lááárín ìlú pàápàá tàwọn ìjòyè. Ó sọ wí pé:

Ohun tí àgbàlagbà yóò fi dáná tí ó fi ní jò

Ìdí rẹ̀ ni a ó báa

Ẹran tí ò le kò wọ́bẹ

Igi tí ó bá ń sèéfí, á sìí yọ ọ́ sígbó.

Òwe yìí túmọ̀ sí pé ẹni tí a mọ̀ wí pé ó hùwà ìbàjẹ́ a yọọ́, á sì fi jófin tàbí kí á rọ̀ ọ́ lóyè.

Àgùntàn yín ò le pasọ èsín dà.

A ò le gba Kámbó lọ́wọ́ imú yín

A ò le gba kàtà lọ́wọ́ akítì.

Ìtumọ̀ òwe ni pé bí á ṣe ń sí wọn lọ́wọ́ ìbàjẹ́ kan ni wọ́n tún ṣe òmíràn.

Tí a bá wo àwọn òwe wọ̀nyí, á rí i pé wọ́n ṣe pàtàkì wọ́n sì ní iṣẹ́ tí wọ́n ń jẹ́ fún àwùjọ nínú fííìmù yìí. Ìṣọ̀lá lò wọ́n láti sọ òkò ọ̀rọ̀ lu àwọn oníwà ìbàjẹ́, èyí sì fi àwọn akópa náà hàn bí ẹni tí ó mọ ìjìnlẹ̀ èdè Yorùbá.

**ÀKÀNLÒ ÈDÈ**

Àkànlò èdè ni lílo àwọn ọ̀rọ̀ tí ó nípọn tí ìtumọ̀ wọn forí mu tàbí takókó tí ó sì jẹ́ wí pé ẹni tí ó bá jẹ́ ọmọ ọ̀dọ̀ àgbà náà ni ó le ní òye nínú irú àwọn ìpèdè tí Akínwùmí tún fi sẹ́nu àwọn akópa inú fííìmù *Agogo Èèwọ̀*.

Díẹ̀ lára àpẹẹrẹ àwọn ìpèdè yìí ni:

Wọ́n fẹ́ kí ń gbégunnu ni o

Kí àwọn lè máa gbowó sọ́wọ́.

(Ọba Bọ̀sípo)

Asẹ̀sẹ̀ jáde akàn lọ̀rọ̀ jogbo

tí ó ń rìn gátagàta.

(Bàbá Ọ̀pálámbá)

Ẹja tí ìwọ̀ yín gbé

Ẹ kò lè dá a jẹtán.

(Olóyè Séríkí)

Kò sí àyè fún ìjẹ mímu tajá tẹran mọ

(Lágbayì Onígẹdú)

Yíyàn tí a tún yín yan

Ìyẹn ni pé, olè ní mọ ẹsẹ̀ olè tọ̀ ni

(Ọba Bọ̀sípo)

Irú àwọn ọnà èdè yìí fi àwọn akópa hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní òye tí ó sì ní ojúlówó ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èdè Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò fọ̀rọ̀ ṣòfò, wọ́n ronú jinlẹ̀ dáradára.

**ÀWÍTÚNWÍ ÈRÒ**

Ònkọ̀tàn náà tún ṣe àmúlò Àwítúnwí Èrò nínú fíìmù rẹ̀. Ó ní:

<u>A ó</u> ṣe ìwádìí

<u>A ó</u> dá owó yín padà

<u>A ó</u> sì fi ìya jẹ àwọn tí ọwọ́ bá tẹ̀ ...

**ÀWÍTÚNWÍ ÀKÙDÉ GBÓLÓHÙN**

<u>Gbáwọn dà</u> síta

<u>Gbáwọn dà</u> sígbó

Gbáwọn dà sẹ́wọ̀n

**ÀWÍTÚNWÍ GBÓLÓHÙN**

Mo ti mọ̀

Mo ti mọ̀

È ṣe tí ọ̀rọ̀ tèmi è é tà létí yín?

**ORIN**

A tún rí ìlò èdè orin náà nínú fíìmù *Agogo Èèwọ̀*.

(i) Lílé: Olú ń réte

Ègbè: Àjà ń réte jà

Lílé: Olú ń réte

Ègbè: Àjà ń réte jà

Lílé: Ilẹ̀ pẹ̀lú Ọlọ́hun

Ègbè: Àjà ń réte jà

(ii) Ó dáni lójú gbangba

Àsá ò gbọdọ̀ wọlé gbẹ́yẹlé

Ọlọ́hun ló màlè faniyọ o hè

Ọlọ́hun ló mà lè faniyọ

A fàparò sábẹ́

À ń gbinkà o

Ọlọ́hun ló mà lè faniyọ.

(iii) Korogbe lórà, ni ò jẹ́ á rílé gbé o

Ọkọ̀ táwọn òyìnbó

Fi ń sèkólẹ̀

Korogbe ló rà, ni ò já rílé gbé.

Akínwùmí lo àwọn orin wọ̀nyí lọ́kan-ò-jọ̀kan, ó lò wọ́n nígbà tí ó yẹ, èyí mú adùn oníye bíye kún fíìmù náà.

**ỌFỌ̀**

A tún ṣe alàbàápàdé ìlò ọfọ̀ nínú fíìmù *Agogo Èèwọ̀* yìí. Bí a ti ṣe rí i nínú àpẹẹrẹ:

(i) Ọ̀rọ̀ pápá ẹnìkan kì í bí ẹja

Ọ̀rọ̀ akèrèǹgbè ẹnìkan kì í bí Odò

Gbogbo ọ̀rọ̀ tí ó délẹ̀ yìí

Kí wọ́n ó gbàgbé mi ni o.

(ii) À rí sáré lọmọde ń réegun

À gbọ́ ǹ gbọ́ obìnrin ń gbóhùn orò

Kí gbogbo yín ó máa bẹ̀rù mi lónìí ó

Kí ẹ gbàgbé èmi Balógun lórí gbogbo ọ̀rọ̀

Tí ó délẹ̀ yìí

Ó di gbẹrẹfu

Mo fọ̀rọ̀ yìí mu tábà

Gbẹrẹfu

Orí kan lejò ní tí ń fi tú gbogbo orí ká.

Irúfẹ́ àwọn ọnà èdè yìí ń fi àwọn akópa hàn gẹ́gẹ́ bí ọmọ ọ̀dọ̀ àgbà, tí ó sì mọ̀ nípa àṣà Yorùbá.

**ÌWÁSẸ̀**

A tún ri ọnà èdè tí ó jẹ́ ti àwíṣẹ. Ìṣọ̀lá tún ṣe àmúlò ẹsẹ Ifá àti ìyẹ̀rẹ̀ Ifá nínú fíìmù náà.

(i) Lílé: Já fàá níròó

Ègbè: Hẹn

Lílé: Ká fàá níbùú

Ègbè: Hẹn

Lílé: Gbọgbọ lọ́wọ́ ń yọ jorí

Ègbè: Hẹn

Lílé: Gbọgbọ ni imọ̀ ọ̀pẹ ń yọ jọ̀pẹ

Ègbè: Hẹn.

(ii) Ifá ló nilé ayé

Olódùmarè ló lọ̀run

Ènìyàn gọ̀ lágọ̀ jù

Wọ́n ṣe báwọn gbọ́n

Ẹ wá wayé òṣèlú

Òṣèlú alábòsí

Ẹ wá wayé òṣèlú o

Wọ́n kówó ìlú sápò ...

(iii) A fipa lówó, wọn kì í kádún

A fi wàràwàrà tọlógùn wọn kì í dọ̀la

Bó pẹ́ títí n ó lówó

Wọ́n ń bẹ labà tí ń jẹsu sísun

Òòjọ́ ẹ̀san ò lọ títí

Kò jẹ́ kọ́rọ̀ ó dun ni

A díá fún adigunla

Tí ó digun sésé

Kò ì pẹ́, kò ì jìnà

Ifá dé aláṣẹ

Opẹ́ abìsẹ́ wàrà ...

**ÀMÚLÙMỌ́LÀ ÈDÈ**

Bákan náà ni Akínwùmí Ìṣọ̀lá lo ìlò èdè tí ó jẹ́ ti àmúlùmálà ẹ̀sìn láti inú Odù Ìrosùn Méjì. Èyí tí Ìṣọ̀lá lò ní ẹnu akópa ni ọ̀nà àrà tí ó sì tún bu yiì kún ẹwà àti adùn eré náà. Ìpèdè náà lọ báyìí:

Ìwòyí di méjì ó dẹ̀rún

Lódífá fún ọlọ́fun agàdí wòran

Wọ́n ní ó rúbọ àìkú

Ó rúu kò kú mọ́

Ẹsẹ̀ tó nà ijó fàá

Ó lanu kótó, orin àwo bọ̀ sí i lẹ́nu

Ó yin àwo, àwo yín Ifá

Ó ń wí pé, Ó ṣeé ó Jésù

A ò máa yìn ọ́

Ó ṣeé ó Jésù

Hàá! Odù rè é ó, Ọ̀yẹ̀kú

Nínú ìwé Dáfídì

Orí kejìdínlọ́gọ́fà ẹsẹ̀ kẹtàdínlógún,

Ó ní

Ikú kíkú kan

Èmi kì yóò kú bí kì í ṣe yíyè lèmi ó yè

Ẹ sọpẹ́ f'ólúwa

Nítorí pé òun lẹ̀dá

Àlì hámúdùlìláhì

Àlàhúmà sẹ́lí

Àmín.

**ÌFỌ̀RỌ̀DÁRÀ**

Bákan náà ni òǹkọ̀tàn náà tún lo ọnà èdè ìfọ̀rọ̀dárà nínú fíìmù náà.

Ó pọ̀nbọ gbọ̀bọ pòǹgbẹ

Ó fìrù ọ̀bọ bọ ọ̀bọ lẹ́nu

Bó bá tètè gbọ́bọ bọ̀gbẹ́

Ọ̀bọ ó gbé ọ bọ̀gbẹ.

**ÀGBÁLỌGBÁBỌ̀**

Onírúurú ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn ọnà èdè ni Akínwùmí Ìṣọ̀lá fi yàwòrán sínú fíìmù *Agogo Èèwọ̀* yìí ni ọ̀nà tí ó rẹwà tí ó sì gbé ògo fíìmù náà yọ, tí ó sì tún fi àwọn akópa náà hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó mọ ìjìnlẹ̀ èdè àti àṣà Yorùbá. Láìsí àní-àní, a rí i pé kò sí àyọdànù nínú gbogbo àwọn ọnà èdè

tí òǹkọ̀tàn sajọ sínú fíìmù rẹ̀ yìí. Gbogbo wọn ló ṣe wẹ́kú pẹ̀lú iṣẹ́ náà. Àwọn ọnà èdè wọ̀nyìí tún fi Ìṣọ̀lá náà hàn bí ẹni tí ó tó gbangba sùn lọ́yẹ tó bá di pé kí á sọ̀rọ̀ nípa èdè tí ó gbámúṣé tí ó sì dùn ún gbọ́, èyí tí ó jẹ́ kí eré náà ó tún bọ̀ dùn, kí ó sì tún lárinrin sí.

## ÌWÉ TÍ A LÒ


Adélékè, D.A. (1995). “Audience reception of Yorùbá films, Ìbàdàn as a case study”. Unpublished Ph.D. thesis, University of Ìbàdàn.

Àlàmú, O. (1990). “Trends in Yorùbá films”: The first decade 1976-1986. Unpublished M.Phil. thesis, University of Ìbàdàn.

Harper, C. (1979). *Collins English Dictionary*. Glasgow, London.

Ìṣọ̀lá, A. (2002). Fíìmù *Agogo Èèwọ̀*, Mainframe films and television production, Lagos, Nigeria.